# Dajudaju nnkan ti mo n bẹru julọ nipa yin ni ẹbọ kekere" wọn sọ pe: Ki ni ẹbọ kekere irẹ ojiṣẹ Ọlọhun? O sọ pe: "Ṣekarimi ni

Lati ọdọ Mahmud ọmọ Labiid- ki Ọlọhun yọnu si i- dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Dajudaju nnkan ti mo n bẹru julọ nipa yin ni ẹbọ kekere" wọn sọ pe: Ki ni ẹbọ kekere irẹ ojiṣẹ Ọlọhun? O sọ pe: "Ṣekarimi ni, Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ fun wọn ni ọjọ igbedide ti wọn ba ti san awọn eniyan lẹsan pẹlu awọn iṣẹ wọn pé: Ẹ lọ ba awọn ti ẹ maa n ṣe karimi fun ni aye, ki ẹ si wo boya ẹ maa ri ẹsan kankan lọdọ wọn?"

[O daa] [Ahmad ni o gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe dajudaju nnkan ti o pọ julọ ti oun n bẹru rẹ lori awọn ijọ rẹ ni: Ẹbọ kékeré, oun ni: Ṣekarimi; ki o maa ṣiṣẹ nitori awọn eniyan. Lẹyin naa o sọ nipa iya awọn oniṣekarimi ni ọjọ igbedide, pe wọn maa sọ fun wọn pé: Ẹ lọ ba awọn ẹni ti ẹ n ṣiṣẹ nitori wọn, ki ẹ si wo boya wọn kapa sisan yin lẹ́san ati fifun yin ni ẹsan lori iṣẹ yẹn?!

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3381

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee